# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Kejilelogoji: Osu Kewa Ojo Kerindinlogun, 2016**

**Akori Oro: Iwa Ole ati Iwa Ooraye** – Apa kini

**Eko kika: Owe 26: 9-16**

## Afihan

Ni aiye isinyi, awon enia ko fe ise se, won feran faaji ju ise sise lo. Awon miran tile ya ole debipe won ko fe lo agbara won ati akoko won fun ohunkohun bikose faaji nikan. Iru awon enia wonyi ma nlo elomiran ni ona alumo-koroyi lati se aseyori tabi lati mu ife-inu won se.

Iwa ole dabi ajakale arun ni, ti ko mo larin awon eya kan, tabi larin awon alawo kan, tabi larin awon ojo-ori kan; sugbon kari aiye ni. Nitoto, awon enia ko fe se akitiyan bikose lori awon ohun ti won le ma fi gberaga tabi eyiti yio fi won han fun gbogbo aiye lori ero-ayara-bi–asa (internet/web). Opo enia ni won ya ole, ti won si tun nko awon enia ni bi ati nse imele, ayafi ti o ba je lori ohun ti yio so okiki ati oruko won di ti gbogbo aiye ni won yio to se akitiyan.

Iwa ole dabi aisan jejere, ti o ti kari gbogbo igbesi aiye awa eda-enia, nitoripe opolopo enia ni won feran iwa ooraye tabi ki won ma se awon ohun adidun aiye dipo ise sise.

Niwon igbati akoko sowon, atipe bi enia ba so wakati kan tabi ojo kan tabi osu kan nu laise ohun ti o ni laari ti yio mu ilosiwaju wa; iru enia be ko le ri awon asilo akoko re gba pada mo. Tori idi eyi e jeki a lo awon akoko wa daradara ni ona ti o bojumu.

Ohunkohun ti o ba ye lati se loni, e mase jeki a daduro tabi so di ola ki ato se, nitoripe kosi eniti o mo ohun ti yio sele ni ola; ki oro wa maba wa dabi oro "atelese ti nfi enu-enu pa ekuro oju ona".

## Isele ninu aiye

Fun ogoro-enia ole sise ti di iwa ati ise won, ni eyiti o je wipe yio nira fun won lati se atunse, ki won le ma gbe igbe-aiye ti nso eso itesiwaju.

**Iwa ole larin awon odo:** Iwa ilora ati olooraye je ohun ti o gberege-jige larin awon odo ode oni, ni awon orile-ede kan l'agbaiye ohun ti won npe ni "ere sise" (hang-out). Awon wonyi yio korajopo si ibikan, ti won yio si beresini se ofofo, besini won yio ma soro awon enia lehin. Won yio ma fi akoko ti won koba lo lati mu idagbasoke ba aiye won sofo, ati akoko ti won koba lo ki won le di enia

pataki l'awujo won a lo lasan: won ko ranti ikilo Paulu aposteli wipe ako gbodo ko lati se ole, ako gbodo lo akoko wa lati ma kiri lati ile de ile gegebi onisokuso ati olofofo, beni ako gbodo se ayonu-so si oro awon elomiran tabi so awon ohun ti ko ye jade lati enu wa **1 Timoteu 5: 13**.
kise gbogbo odo ti won je ole ni won feran ayonuso ati ofofo, tabi ki won ma so awon ohun ti ko ye jade. Opo ninu won feran ki won ma se ere tabi bani soro lori ero ayara-bi-asa (internet/web). Awon wonyi yio pa eko won ti, won yio gbe ise-ile ti o yeki won se si egbekan, besini won koni nani ise Oluwa.

**Iwa ooraye ni ibi ise:** Opolopo enia ninu agbaiye ni won nse ole lenu ise won. Ti o ba je wipe awon ni oludasile ile-ise, won ama wani imurasile, won a jafafa leni ise, beni won a si ni itara ki ile-ise na bale se aseyori. Sugbon ti o ba je wipe a gba won si ise ni, won a ma se ole ati ilora lenu ise won. Ayafi ti o ba ni eto kan ti won yio gba, tabi ohun iwuri ti ao se fun won, ti won ba se ise won bi ise; bibeko iwa ole yio farahan larin awon osise yi.
Iwa ole yi je ohun ti o gbile larin awon osise-ijoba jakajado gbogbo aiye. Larin awa ti a ngbe apa ariwa-iwo oorun ni orile-ede Nigeria ti ise Yoruba; won ma nsoro kan wipe "Ise ijoba kise aseku" eyiti o tumo si wipe fi owo pa ise, ki o si beresini se ooraye kakiri. Ni opo orile-ede nla ni agbaiye, pupo ninu awon osise-ijoba yio wa lati fi owo si iwe wipe awon wasi ibi ise, sugbon won yio pada losi ile won.

**Iwa ole ati ooraye ninu agbala Oluwa:** Nigabti awon enia ba losi ile-Oluwa lati lo gbadura, opo yio gbadura kusekuse, lehin-na won yio bere ayonuso sise. Nigba miran, e o ri won ti won joko ni isori-isori ti won yio ma to-ejo ti kole mu idagbasoke ba agbo-Oluwa. Awon oro ti won yio ma so je gboyi-soyi-oro, ti o le fa ipinya ati ikunsinu ninu ijo tabi ki o tu ijo-Oluwa. Igba miran, won ama tu asiri ijo Olorun ni gbangba ni ona ti o le mu ote wa.
Won a ma so ohun ti oju won ko to nipa awon enia ninu ijo, won ti gbagbe ikilo bibeli ti o wipe "iwo ko gbodo lo soke lo sodo bi olofofo larin awon enia re ….." **Lefitiku 19: 16**.
Ohun ti o je iyalenu ni wipe, awon osise ninu ijo ti o yeki won je olufokansin ati apere rere, ko gbehin ninu iwa buburu yi. Awon alufa ti won ngba owo-osu lati ma ko awon enia ati lati bojuto agbo Oluwa, awon pelu wa ninu awon olofofo ati awon agboyi-soyi wonyi. Awon alufa wonyi nfi ise ati ojuse won sile, lati ma se ise aileso okunkun yi.
Awon iranse-Oluwa ti gbagbe eje tabi ileri ti won se nigbati won gba ise-iranse, wipe nwon yio ma dabobo agbo aguntan Oluwa ati lati bojuto ogba-ajara re.

Won ni lati ni arojinle ki won si yipada, nitoripe " enikeni ti a ba fun ni pupo, lodo re li ao gbe bere pupo: lodo eniti a ba gbe fi pupo si , lodo re ni ao gbe bere si i" **Luku 12: 48**.
Akoko tito lati siwo iwa ole ati iwa ooraye ninu ijo Oluwa, niwon igbati o je wipe ile adura fun gbogbo orile-ede li ile Oluwa **Mark 11: 17**. Nitorina, ni igbakugba ti a ba wa ni ile Oluwa tabi ayika re, e ma gbadura karakara, ki e si ma se awon ohun ti yio mu idagbasoke ati itankale ba Ihin-rere, laisi ayonuso tabi gboyi-soyi kankan.

**Asiwaju iyanu ni Olorun**

E mase si mi gbo, nko wipe awa enia ko gbodo sinmi tabi gbadun ara re, sugbon ohun gbogbo ni lati je iwontun-wonsi. Niwon igbati o je wipe "owo ti o ba dile ni Esu nyalo" mase je ole, ki Satani maba lo o fun ogo arare.
Olorun Olodumare fi apere lele, nigbati O se ise fun ojo mefa, ti o si sinmi fun ojo kan **Genesisi 2: 1-2**.
Lotito, awa enia le mani agbara ati se ise ipa-mefa, ki a si sinmi fun ipa-kan, sugbon ako gbodo ya ole, bikose ki a sa gbogbo ipa wa. Awon enia ma nsoro wipe "ise sise laisi isinmi ma ntako alafia ago-ara ni", lotito ni, sugbon e jeki akoko ere sise yin wa ni iwontun-wonsi, ki o maba di iwa ole tabi imele.

**Eegun ni iwa ole:** Opolopo enia ni won jafafa, ti won si ni akitiyan pelu iforiti nipa oko-owo tabi ise-oojo won, sugbon ti won nse imele ati ole; nigbati o ba kan ise Oluwa. Bibeli wipe " ifibu ni eniti o se ise Oluwa ni imele …". Nitorina, mase fi oju pa ise Oluwa re, mase se alaibikita fun ise Oluwa, besini o ko gbodo ko ise Baba re ti nbe ni orun sile laise **Jeremiah 48: 10**.
Ti o ko ba fe di eni-eegun, mase fi imele se ise Oluwa. O gbodo se ise Oluwa tokantokan, ni aisi etan tabi agabagebe tabi iwa ole; Ki ise re ba le se itewogba niwaju Oluwa.
Ti o ba ni itara ati akitiyan fun oko-owo re tabi fun ise-oojo re nikan, sugbon ti o ko nani ise Oluwa, ise re koni itumo niwaju awon orun. Toripe, o ti ko idi ti Olorun fi s'eda enia sile, ti ise lati se ise re. Torina, yipada loni ki akoko to koja lo.

## Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Ketalelogoji: Osu Kewa Ojo Ketalelogun, 2016**

**Akori Oro: Iwa Ole ati Iwa Ooraye** – Apa keji

**Eko kika: Owe 26: 9-16**

Eko yi yio tesiwaju nipa ijora-eni ti o wa larin iwa ole ati awon iwa ibaje.

**Ijora-eni larin Iwa ole ati awon iwa ibaje**

Opolopo ijora- eni ati isopo ni o wa larin iwa ole ati iwa ibaje, nitorina mase jeki iwa ooraye ba aiye re je.

**Ona ole dabi igbo egun:** Ona ole enia je wiwo, atipe igbesi-aiye ole enia kun fun isoro gegebi eniti nrin ninu igbo egun. Bibeli fi idi re mule wipe “ ona ole dabi igbo egun, sugbon ona olododo kunakuna ni” **Owe 15: 19**. Bi o ko ba fe ki igbesi-aiye re dojuru ki o si kun fun isoro, mase ya ole. Ya kuro ninu iwa ole bi o ko ba fe ki ona re nipa ti emi dabi igbo egun, ti o ngun enia, ti o ole ya’ni lara, ti o si le lo’mo enia lati fi enia sinu ewu.

**Ijakule ati ifasehin ni igbehin ole:** Ole ko ni ere, beni awon ole enia ko ni iforiti eyiti o ma njeki won so awon anfani nu ni opo igba. Fun gbogbo awon ole, ati pese awon ohun amaiye-derun je eru-wiwo fun won, nwon a si ma wa awon enia ti yio ba won ru eru na. Ohunkohun ti awon ole ba bere, nwon ki le pari re ki won to jawo, nwon ti gbagbe wipe “eniti o ba yowo kuro ninu sise nkan ki yege, beni eniti yio yege koni yowo titi yio fi pari re”. Idi eyi ni Iwe Owe se so wipe “ole pa owo re mo sinu isaasun ko si le yo o jade pada wa si enu re” **Owe 26:15, 19: 24**. Bi o ko ba fe se aseyowo lori ohun rere ti awon elegbe re nse aseyori re pelu irorun, mase se ole sugbon ni iforiti.

Awon ole enia koni iforiti, bi won ba bere ise kan nwon kile pari re; idi eyi ni o se soro fun won lati se aseyori lori awon adawole won. Iwe mimo wipe “ole enia ko mu ohun ode re; sugbon lati je alapon enia, oro iyebiye ni” **Owe 12: 27**. Nitorina, ti o ba nfe se aseyori ni ile alaaye, o ni lati sise karakara pelu eri-okan ti o dara.

**Iwa ole nfa irora ati inira:** Awon ole ni ogun aiye ara won, ti nwon si nfa awon wahala tabi isoro ti won ndojuko. Awon wonyi ma nlero wipe awon gbon ju awon enia toku lo, toripe nwon ama lo ogbon-ewe ki won maba se ise ti o je

ojuse tabi ipin tiwon. Bibeli wipe " bi ohun kikan si ehin, ati bi efin si oju, beni ole si eniti o ran a ni ise". Bi o ko ba fe irora ti kose fi enu so ninu aiye re, ti yio si mu awon ti o gba o si ise binu, mase ya ole **Owe 10: 26**. Bi o ko ba fe ki inu Olorun Olodumare ti o ran a nise si araiye baje, mase ya ole.

**Iwa ole nba aiye enia je:** Iwa ole je okan lara awon ohun-ija ti Satani nlo l'odi si awa eda-enia, o si ni agbara debipe o le ba aiye enia je, bi enia ko ba kiyesara. Iwe mimo sapejuwe awon ole enia wipe eniti o lora ni sise ise re, arakunrin jeguduragudu enia ni. Eyi tumo si wipe iwa ole ati iparun, omo-iya niwon, toripe won ti wonu ara won gegebi egungun ati eran, laisi eniti o le ya won **Owe 18: 9**. Bi o ko ba fe ajalu ninu aiye re, ti o ko si fe ba ojo-iwaju re je; mase se ise Oluwa pelu iwa ole tabi iwa imele.

## Bi ati nmo awon ole enia

O ni opolopo awon afihan tabi oye ti o le ranni-lowo lati mo awon ole enia, besini ao soro nipa won gegebi ifilele bibeli.

**Awon enia arise-mase:** Ainise-lowo tabi airise-se gba gbogbo aiye kan lode oni, amo awon orile-ede kan wa ni agbaiye tiwon ni opolopo ise, sugbon awon enia ibe je ole ati arise-mase. Bi o tile je wipe won nkede wipe aye ise si sile ni awon ile-ise ti nbe nibe, awon ole enia ti nbe ninu awon orile-ede yi koni lo kowo-bowe lati sise tabi ki won wa ise si awon ibomiran. Awon wonyi feran ki won ma gba owo-ijoba tabi ki won am toro onje ju ki won sise lo. Ni ile Yoruba awon wonyi ni a ma npe ni "arise mase baba ole". Awon ole enia yi yio wa idi kan tabi esun kan ti won ko fi le sise. Won le wipe nitori otutu, tabi nitori ojo, tabi oorun, besini won ko ni tu ile won. Nitorina, ni won yio fi ma sagbe ni igba ikore, toripe won ki yio ni onje kankan lati je **Owe 20: 4**. Bi o koba diromo anfani ise ti o ni loni, yio nira fun o lati gbo bukata aiye re.

**Okan ole nfe ohunrere sugbon o se alaini:** Awon ole enia nife ohun ti o dara, amo kiun tabi aini nkankan ni o ma nje ipin won, nitori aife-sise won. Okan awon ole a ma pohungbe fun awon ohun amaiye-derun, sugbon won ki i ni nkankan. Laifa oro-gun ole enia kole ni ohun ti o nfe, ayafi nipase etan, sugbon okan awon alapon yio ni anito ati aniseku **Owe 13: 4**. Wa lara awon alapon enia, ki a le fi ohun rere te o lorun.

**Awon enia ti won feran orun:** Enikeni ti o ba feran orun-asunju ati awon awon enia ti won ki fe dide lori ibusun won, ole enia ni won. Bibeli wipe " bi ilekun ti

iyi lori iwakun re, beni ole lori eni re" **Owe 26: 14**. Awa eda-enia ni lati sun ki a si sinmi ki ago-ara wa le jipepe, sugbon a ni lati se ohun gbogbo ni iwontun-wonsi. Mase nife orun sisun ki o maba ya ole.

Ni igba ikehin yi, awon ole enia ni o ma nsun fonfon. Nigbati eyi ba sele won afi emi tiwon ati emi awon ara yoku sinu ewu. Fun apere ti ijamba ina tabi idagiri ba sele, yio soro lati ji iru awon enia be kuro loju orun, ni eyi ti o si le muki emi won segbe sinu isele na. Awon onimele enia je ole, toripe opo nkan ti yio so eso rere ni won le se ni awon akoko ti won fi nsofo nipa ooraye **Owe 19: 15**. Lati isinyi lo, ko o bi enia ti nsun orun ti kise fonfon, mase se olooraye mo, ki a maba ka o mo awon ole enia ti yio sagbe nigba aiye won.

**Ole enia lero wipe on gbon:** Nitoripe awon ole enia ma nlo elomiran nipa etan ati alumo-koroyi lati mu ipinnu won se, awon wonyi ma nlero wipe awon gbon ju awon alapon enia lo. Opo awon ole enia ni nma wipe "mo ni ogbon ju awon toku mi lo", e jeki nso fun won, e ko ni ogbon-Oluwa bikose ogbon-imele ati ki a sa fun ise. A kowe re wipe "ole gbon ni oju ara re ju enia meje lo ti nwon le fi ogbon dahun oran" **Owe 26: 16**. Awon ole enia ko gbon, sugbon won je ole-afajo ti nma sa fun ise ati ojuse won.

**Awon ole je obun ati eleeri:** Ona ti rorun ju lati mo ole enia ni ki a se ayewo ile won, nitoripe, ile nwon yio doti yio si wa ni jaku-jaku. Ni igbamiran, ile awon alapon enia miran ti ise bati pa l'ori le doti; sugbon opolopo ile awon alapon enia ni yio wa ni imototo ti ohun gbogbo yio si wa ni tito finifini.
Ni opo igba ti e ba de ibi-ise awon ole, eo ri wipe o doti, ti ohun gbogbo yio si wani idarudapo. Irisi awon ole papa ama fi won han, irun ori won yio wani yegeyege, aso won yio wani rirun ati irisi won bi ohun ti kori itoju **Owe 24: 30-31**. Bi o ba feki gbogbo aiye mo wipe iwo kosi lara awon ole-afajo atipe oni ogbon lori, toju ile re, ibi-ise re ati irisi re; jeki won wani imototo ati finifini.

**Ole ni nkigbe idagiri tabi ijaiya lori eke:** Enikeni ti o ba nkigbe ijaiya lori eke, tori ki won maba sise, ole enia ni. O je ohun ti o tankale larin awon ole enia ki won ma kigbe idagiri lori eke, tori ki won ba le pe'se sile tabi ki won bale yan ise l'odi; ni ona ti won yio si tun fi tiwon koba ti awon elomiran ki awon na maba le sise **Owe 22: 13, 26: 13**. Mase fo'ya nibiti eru kosi, toripe Oluwa ko fun wa ni emi iberu bikose emi igboya.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Kerinlelogoji: Osu Kewa Ogbon ojo , 2016**

**Akori Oro: Iwa Ole ati Iwa Ooraye** – Apa keta

**Eko kika: Owe 26: 9-16**

A ntesiwaju ninu eko yi, nigbati ao gbajumo awon ona ti a fi le bori iwa ole.

**Bi enia ti le bori iwa ole**

Awon ona ti a fi le bori iwa ole ati iwa ooraye ni ao menuba ni itele-ntele gegebi ati ko sinu iwe yi:

**Yago fun orun asun-pajude:** Gegebi ati so teleri wipe awon enia ti won ba fe bori iwa ole ko gbodo nife orun sisun tabi ki won nife orun asun fonfon, sugbon won ni lati jeki orun sisun won wa ni iwontun-wonsi. Orun asunpajude je okan lara awon ailera ti awon onise-ilera oyinbo npe ni ipa-so-mia, enikeni ti eyi ba sele si gbodo bojuto kiakia nitori ewu ti nbe ninu re.

Olorun ninu akainiye ogbon re, mo wipe ewu wa ninu oru asunpajude, idi niyi ti o fi se ikilo fun wa ninu bibeli wipe "mase fi orun fun oju re, tabi ogbe fun ipenpeju re" **Owe 6: 4**. Mo gbadura wipe, o koni ba aiye re je nipa orun asundato ati ogbe.

Apoju ohunkohun nipa ti ara ko dara, idi niyi ti iwe mimo se jeri si wipe "omuti ati ojeun ni yio di talaka; ole ti nsun orun asunpajude ni yio si fi akisa bo ara re" **Owe 23: 21**.

**Gbadura ki emi orun-ijika ma bale o:** Jeki iwa re wa ni ibamu pelu eko inu bibeli, ki o si gbadura ki emi orun-ijika eyiti Olorun Olodumare fi nje awon alaigboran niya maba bale o. Gegebi ati kowe re wipe "Olorun ti fun won ni emi orun: oju ki nwon ki o ma le woran, ati eti ki won ki o ma le gboran, titi o fi di oni-oloni" **Romu 11: 8, Isaiah 29: 10**. Ojuse re ni lati gbadura gidigidi ki emi ilowowo ati emi iye-rira maba muki o so awon ebun-emi ti a fifun o nu .

**Wa ni igbaradi:** O ni lati wani igbaradi ati imura-sile, ki o si gbe awon igbese igbagbo fun igbala okan re, lati le pa iwa ole re patapata kuro ninu aiye re. Mase fi igbala re d'ola, nitoripe o ti to wakati nisisiyi fun o lati ji loju orun: nitori nisisiyi ni igbala re sunmo etile ju igbati iwo ti koko gbagbo lo **Romu 13: 11**. O ni lati sa gbogbo ipa re lati gba aiye re kuro lowo iwa ole ati emi re kuro lowo Iparun.

**Wa ni airekoja ki o si ma sona:** Niwon igbati bibo Jesu Kristi yio dabi ole ni oru, atipe kosi eniti o mo ojo ti Oluwa yio se abewo aiye re, lati fun un ni idahun lori awon ebe ati adura re, ti o ti ngba lati ojo pipe. Fun idi eyi, o di ewo fun wa lati sun ninu emi, bi awon enia toku ninu aiye ti nse, sugbon a gbodo wani imura-giri. Nitorina a ni lati wa ni airekoja ki a si ma sona bibo Oluwa **1 Tessalonika 5: 6**. Bi enia ba sun orun asunpajude ninu ara o je ohun ti o buru, sugbon bi enia ba sun ninu emi, o je ohun ti o buru-jai. Nitorina, mase sun ninu emi, sugbon wa ni airekoja, ki o si ma sona; ki a ba le ka o ye, nigbati Kristi Oluwa ba padade.

**Mase je onilora:** Awon enia ti won bati pinnu ti nwon si setan lati bori iwa ole, koni je onilora sugbon nwon yio jafafa, ki won ba le se afarawe awon ti nwon ti ipa igbagbo ati suru jogun awon ileri Olorun **Heberu 6: 12**. Tele apere awon enia ti won jogun ileri Olorun nipa igbagbo ati suru. Ki iwo na ba le jogun awon ileri Olorun ti a ko sinu bibeli, ki o si le fi ogun-rere le'le fun iru-omo re.

**Sin Oluwa tinutinu:** Ona ti o daraju lati dagbere fun iwa ole, tabi ju iwa ole sile, ni ki enia o sin Oluwa tinutinu; ki o sise fun Oluwa tokantokan laisi imele. Ki iru awon enia be jeki ina Emi mimo majo ninu aiye won, ki won ni igbona okan si Ihinrere, besini ki won ma fi gbogbo ipa won ati itara sise Oluwa lai-bojuwehin **Romu 12: 11**. Bi o ba feki Oluwa so iwa ole di itan ninu aiye re, sin Oluwa ninu ewa iwa-mimo.

## Iyorisi iwa ole ati iwa ooraye

Ao soro nipa awon iyorisi tabi igbehin iwa ole ati iwa ooraye.

**Iwa ole nba aiye enia je:** Ife okan ole ni yio se iku pa, nitoriti owo re ko ise sise. Edun okan ole je ohun ti o l'ewu, toripe o nfe ohun giga, besini ko fe sise fun awon ohun wonyi. Awon wonyi ni Yoruba ma npe ni "eniti kofe de odo ki o to pon omi" **Owe 21: 25**. Mo gbadura wipe iparun ti iwa ole nfi t'ore koni je ipin re, besini iwo ki yio ku iku ebi.

**Iwa ole nso enia di talaka:** Enikeni ti o ba de owo ni ise sise ati awon ti nse ooraye nibi ise yio di talaka, amo owo awon alapon ni nmu ola wa. Mo feki o di mimo fun awa enia wipe iwa ole ni nmu osi ati iise wa, ole owo ni o nso enia di talaka, ole enia yio si pada di talaka **Owe 10: 4**. Botiwu kope to awon ole yio pada di talaka ni, ayafi ti won ba yipada ti won si se atunse.

**Ole enia ni nse eru fun egbe won:** Awon ole ni o ma nse eru fun egbe nwon, awon ni nwon ma nse akobata fun egbe nwon, ti nwon yio si ma sin awon iiro nwon; nitori iwa ole nwon. Bibeli wipe " owo alapon ni yio se akoso, sugbon ole ni yio wa labe iru-sisin" **Owe 12: 24**. Oluwa Olorun ti a njosin fun yio se wa ni okan lara awon asiwaju ninu esin igbagbo.

**Iwa ole ko ni ere:** Gbogbo ise gidi ati laala ni o ni ere pupo, sugbon iwa ooraye nsoni di akuse. Eyi tumo si wipe bi o ba sise karakara, iwo yio ri owo-oya ti iwo yio ma fi bojuto aini re; sugbon ti o ba joko lasan ti o nse aroye, iwo yio di akuse. Nitorina, ninu gbogbo laala li ere pupo wa: sugbon oro-enu, lasan ni **Owe 14: 23**. Ise sise ni nmu ere wa, osise ni o ngbagbe iise, toripe oro-enu ati iwa ooraye ko le pese akara/buredi si ori tabili re, bikose ki o so enia di akuse.

**Iwa ole nfi ile enia sinu ewu:** Ile awon ole wa ni ewu hihu ati idibaje, ni ona ti yio jeki iwa ti o bojumu dinku, agbara ati ilera yio si re'le, besini ajose enia pelu Olorun yio si rehin. Ni afikun nipa ole owo ati iwa ooraye, ile a si ma jo, eyiti o tumo si wipe; awon wonyi yio so awon ebun Oluwa ti kose fi owo ra, ti osi se iyebiye nu ninu aiye nwon **Oniwasu 10: 18**.

## Sora fun iwa ooraye

Ni iwon igbati iwa ole ati iwa ooraye je omo-iya ti a ko si le pin won n'iya, o ni lati kiyesara ki o maba di olooraye. Ri wipe o nse awon nkan ti o l'eso ti yio si mu itesiwaju ba aiye re ati ajose ti nbe larin iwo pelu eleda re ni gbogbo igba.

Paulu kigbe ikilo yi ninu episteli re si awon ara Tessalonika wipe, ki nwon yera kuro lodo olukuluku arakunrin/arabinrin ti nrin segesege gegebi olooraye, ti ki isi se gegebi ilana ti won gba lowo re **2 Tessalonika 3: 6**. Arakunrin ati arabinrin yera fun awon ti won npe ara won ni onigbagbo, ti won ngbe igbe-aiye ooraye, ti won ko si tele ilana Bibeli. Pataki julo, awon ti won de owo ni sise ojuse tabi ise won, pelu awon ti won sa fun ati se ojuse won; ti won si ko ojuse won sile laise.

**Edidi: Ifihan 3: 19:**

Gbogbo awon ti emi ba fe ni mo nbawi, ti mo si nna: nitorina ni itara, ki o si ronupiwada.